Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial II | p. 143-153 | jul./dez.2025.

# Àgbéyẹ̀wò orísirísi ìlò èdè tí ó jẹyọ nínú ìwé ìtàn àròsọ *kò sọ́rọ̀* tí layọ̀ ògúnlọlá kọ

**Akinniyi Williams AKINLABI** *

ORCID iD https://orcid.org/0009-0009-6852-3266

**ÀṢAMỌ̀**

Ìlò èdè Yorùbá láàrin àwọn ọmọ kááárọ̀-oò-jíire tí n di ohun àfiṣẹ́yìn tí éégún n fisọ. Ìdí gan nìyí tí olùwádìí ṣe gùnlé kókó iṣẹ́ yìí láti ṣe àwárí àwọn àkànlò èdè ayàwòrán tó forí nù jáde ní pàápàá jùlọ nínú ìwé Ìtàn Àròsọ Kò Sọ́rọ̀. Iṣẹ́ yìí ṣe àwárí àwọn àkànlò-èdè bíi ìyán-ọ̀rọ̀-fẹ́rẹ́, ìṣewẹ́kú, ìfirógbòyeyọ, ìfirómọrísì, ìfirósínrójẹ, ìfohùnpènìyàn, òwe, ìfènìyànpohun àti àfiwé tààrà. Iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí ṣe àgbéyẹ̀wò àwọn ìlò èdè wọ̀nyí nípa lílo tíọ́rì soṣíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ tó tẹ̀lé èrò Karl Marx. Ní ìparí, iṣẹ́ yìí dábàá fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tó n kọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá, àwọn olùfẹ́ èdè Yorùbá, àwọn ilé iṣẹ́ rédíò àti tẹlifísàn tí ń gbé èdè Yorùbá lárugẹ láti máa ṣe àmúlò àwọn àkànlò èdè ayàwòrán wọ̀nyí nínú ìgbòkègbodò wọn lójoojúmọ́, nípa síṣe èyí, èdè wa kò ní lọ sí oko ìparun.

## Ìfáárà

Yorùbá jẹ́ èdè tó lààmì laka, ìtumọ̀ èyí ni pé nínú gbogbo ẹ̀ka àwùjọ tàbí ìgbé ayé oríléẹ̀dè ni a ti rí ọwọ́jà èdè Yorùbá. Bí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa èdè Yorùbá a ń sọ̀rọ̀ nípa èdè àwọn ọmọ kááárọ̀-oò-jíire, èdè tó kún, èdè tó rẹwà, èdè tó lóòrìn, tí ó sì gbajúmọ̀ lóríléẹ̀dè yìí àti ní àwọn orílẹ̀ èdè mìíràn. Èdè jẹ́ ohun àdámọ́ tí Elédùmarè fi jíǹkí àwa ọmọ adáríhun, òhun ló sì ya àwa ènìyàn sọ́tọ̀ sí àwọn ohun abẹ̀mí yòókù. Èdè ní í ṣe pẹ̀lú ìdàgbàsókè àwùjọ àti ìgbé ayé oríléẹ̀dè pàápàá jùlọ ètò ọ̀rọ̀ ajé, àmúlùúdùn, ètò ẹ̀kọ́ àti ìṣèlú.

Àwọn ẹwà inú èdè náà ni a mọ̀ sí àkànlò èdè ayàwòrán. Àkànlò èdè ayàwòrán yìí pọ̀ lọ́pọ̀ yanturu, ó dà bí i máyàmí sí iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀, èyí tí àwọn òǹkọ̀wé máa ń ṣe àmúlò. Irúfẹ́ àwọn àkànlò èdè wọ̀nyí gbọ́dọ̀ jẹ àṣàyàn. Kí iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ kan tó le kún ojú òsùwọ̀n a nílò ọ̀pọ̀lọpọ̀ èròjà amédèrẹwà. Onísẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ máa ń mọ̀-ọ́n-mọ̀ lo àwọn àkànlò-èdè ayàwòrán wọ̀nyí ni pẹ̀lú èròngbà àti fún àwọn olùgbọ́ rẹ̀ ní ìtumọ̀ kíkún nípa iṣẹ́ ọnà náà lọ́nà tí ó gbà fi ọgbọ́n, òye àti ìmọ̀ tí ó wà nínú irúfẹ́ irú iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ bẹ́ẹ̀ hàn.

Ìlò èdè nínú iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ máa ń fún iṣẹ́ lítíréṣọ̀ ní ẹwà. Bí onísẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ bá ṣeṣe àmúlò èdè sí ni yóò sọ bí ó bá ṣe gbọ èdè tó hàn, onísẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ kìí sàdéédé lo èdè ayàwòrán lásán, bí kò ṣe pé láti fi wakọ̀ kókó kan pàtó gúnlẹ̀ nínú iṣẹ́ rẹ̀ lọ́nà tí yóò mú kí àwágúnlẹ̀ èrò rẹ̀ yìí wọ olùgbọ́ tàbí òǹkàwé lára (Oyèrìndé àti Alímì, 2011).

Iṣẹ́ olùgbọ́ àti òǹkàwé tàbí onísẹ́ láméyítọ́ ni láti fa àwọn ìlò èdè ayàwòrán èyí tí òǹkọ̀wé fi ń wa kókó ọ̀rọ̀ rẹ̀ gúnlẹ̀ nínú iṣẹ́ ọnà jáde, kí ó sì sọ ìdí tí òǹkọ̀wé ṣe lò wọ́n ní ibi tí ó gbé lò wọ́n, èyí ni yóò jẹ́ kí á mọ̀ pé iṣẹ́ tí onísẹ́ ọnà lítíréṣọ̀ rán yé olùgbọ́ tàbí òǹkàwé rẹ̀ dáadáa.

Layọ̀ Ògúnlọlá jẹ́ ọmọ elédè tó mọ èdè, ó sì hun iṣẹ́ ọnà rẹ̀ pẹ̀lú àwọn àkànlò èdè ayàwòrán èyí tí ó jẹ iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí lógún, àpilẹ̀kọ yìí ṣe ìtúpalẹ̀ díẹ̀ lára ìlò èdè Layọ̀ Ògúnlọlá nínú ìwé rẹ̀ *Kò Sọ́rọ̀*, tí a sì sọ ìtumọ̀ àti ìdí tí ó fi lo òkọ̀ọ̀kan wọn ní ọ̀gangan ibi tí

* Department of yorùbá, Federal College Of Education, Yola, A Yoruba lecturer from Federal College of Education, Yola, Adamawa state. I have been a tutor for the past eighteen years. Presently I am undergoing my doctorate degree at Department of Linguistics and African Languages, university of Ibadan in Yoruba literature, E-mail: awakinlabi@fceyola.edu.ng

wọ́n ti jẹ yọ pẹ̀lú lílo abẹ fẹ́lẹ́ ìmọ̀ ìyẹn tíọ́rì Soṣíọ́lọ́jì Lítíréṣọ̀ tó tẹ̀lé èrò Karl Marx láti fi la tifuntẹ̀dọ̀ kókó kọ̀ọ̀kan kalẹ̀.

**Tíọ́rì Ìṣàmúlò: Tíọ́rì Soṣiọlọ́jì lítíréṣọ̀ tó tẹ̀lé Èrò Karl Marx**

Tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa tíọ́rì soṣíọ́lọ́jì tó tẹ̀lé ìlànà àti èrò Karl Marx, tíọ́rì yìí kìí ṣe tíọ́rì òní, ó ti pẹ́ tí ó ti dáyé. Olùdásílẹ̀ tíọ́rì yìí ni Karl Marx. Láti nǹkan bí ọdún 1840 ni Karl Marx fúnra rẹ̀ ti ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí àwùjọ àti àṣà, ṣùgbọ́n ní nǹkan bí Sẹ́ntúrì ogún ni tíọ́rì náà búrẹ́kẹ́ láwùjọ àwọn akadá. (Adéyẹmí, 2006, o.i.36).

Tíọ́rì yìí jẹ́ àbájáde ìrònùjinlẹ̀ Karl Marx àti Fredrick Engels nínú ìwé òṣelú kan tí wọ́n pè ní *The Ẹommunist Manifesto*. Àwọn àlàyé inú ìwé ètò ìlànà òṣèlú yìí ni àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì náà ti fẹ̀ lójú. Lára wọn ni Lenin, Mao, Lucas, Goldmann, Bredcht àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Nínú èrò Karl Marx àti Engels, wọ́n ṣe àkíyèsí rẹ̀ pé ìtàn ọmọnìyàn láyé jẹ́ ìtàn ìjàgbara tàbí ìkọlura agbára, ète àti ọ̀nà tí ẹ̀dá ń gbà láti gba ara rẹ̀ kúrò lábẹ́ àjàgà ẹlòmíràn tàbí ìjàgbara kúrò lábẹ́ àwọn afiyàjẹni. Eagleton (1996) ṣe ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ àlàyé lórí èyí, ó ní tíọ́rì tí ó tẹ̀lé ìlànà àti èrò Karl Marx yìí jẹ́ èyí tí ó jẹ mọ́ tíọ́rì sáyẹ́nsì lórí àwùjọ ènìyàn, ohun tí ó sì jẹ́ ajolórí rẹ̀ ni akitiyan tí atọkùnrin àtobìnrin ń ṣe láti jàjàgbara kúrò lọ́wọ́ àwọn arẹ́nijẹ. Marx àti Engels fẹsẹ̀ rẹ̀ múlẹ̀ pé ìgbà kan kì í lọ bi òréré ni ọ̀rọ̀ ilé ayé, nígbà nígbà ni ayé rí, wọn wo sàkun ìtàn ayé, wọ́n sì pín ìgbà sí àwọn ìpele wọ̀nyí. Ìgbà àìmọ̀ tí a lè pè ní ìgbà tí ayé wà lórúnkún, ìgbà oníṣàkọ́ọ̀lẹ̀, ìgbà ìjọba olókowò aládàánlá àti ìgbà ètò alájọni. Kò sí èyí tí kò ní àbùdá tirẹ̀ lọ́tọ̀, ṣùgbọ́n ètò ọrọ̀-ajé olókoòwò aládàánlá ló gbajúmọ̀ jù. Ètò yìí fàyè gba ìgabalé irú èyí tí ó wọ́pọ̀ nígbà ìjọba oníṣàkọ́ọ̀lẹ̀ (Agu, 2008, o.i.167).

Ètò ọrọ̀-ajé olókoòwò aládáàńlá fàyè gba ìpínṣẹ́ṣe, ó sì fàyè gba ìmọ̀ ẹ̀rọ tó lágbára. Ètò okòwò fẹjú sí i, ó sì mú ìtẹ̀síwájú bá àwùjọ. Ṣùgbọ́n nípa ètò ọrọ̀-ajé wọn, ọká bímọ lẹ̀, ó bóró ni, osùn òkèèrè lejò ń kùn, ètò ọrọ̀-ajé yìí fàyè gba ìrẹ́jẹ àti ìkọlura agbára àwọn tí ó fẹ́ ṣèlú, nítorí àwọn tó bá ń ṣèlú ló lágbára àti mójútó ètò ọrọ̀-ajé, nípa ìdí èyí ìlòdì sí ìjọba a máa wá láti ọ̀dọ̀ àwọn tí à ń gàbalé lórí. Ìtanú àti ká rẹ́nijẹ máa ń pọ̀ ní àwùjọ elétò ọrọ̀-ajé olókòwò aládàánlá. Nítorí pé ọwọ́ àwọn ènìyàn péréte ni ọrọ̀ ìlú máa ń wà (Adéyẹmí, 2006, o.i.36). Giddens (2006, o.i.69) náà gbà pé ọ̀wọ́ àwọn ènìyàn péréte ni ọrọ̀ ìlú máa ń wà gẹ́gẹ́ bí àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí ṣe sọ, ní èyí tíó máa ń fa ìrẹ́jẹ àti ìmúnisìn. Gẹ́gẹ́ bí ọ̀rọ̀ Gidden ṣe lọ:

> Marxist theorists contend that social institution and practices continued because powerful groups have the ability to maintain the status áuo. Change has significanẹe sẹene it is needed to correẹt injustices and inequalities.
>
> (Àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì Marx sàlàyé pé ètò àti ìgbòkègbodò àwùjọ ń tẹ̀síwájú nítorí pé àwọn alágbára kan láwùjọ fẹ́ kí ètò máa lọ bẹ́ẹ̀. Pàtàkì ni àyípadà rere jẹ́ nínú ètò ìgbòkègbodò àwùjọ nítorí pé ó lágbára láti ṣe àtúnṣe tó jọjú nípa ìrẹ́nijẹ àti àìṣedéédé láwùjọ)

Atótónu tí a lè ṣe nípa ọ̀rọ̀ Giddens òkè yìí ni pé ètò láti jàjàgbara kúrò lọ́wọ́ ìrẹ́nijẹ múmú láyà àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí àti pé ọ̀nà àti ja àjàbọ́ lọ́wọ́ àwọn olórí, alágbara tàbí aláṣẹ pín sí oríṣìíríṣìí, èyí sì máa ń fa aáwọ̀.

Adéyẹmí (2006, o.i.37) ní àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí gbà pé ara ètò àti ìhun àwùjọ ni lítíréṣọ̀. Àwọn ètò àti ìhun àwùjọ yòókù ni ìṣèlú, òfin, ẹ̀sìn, ìmọ̀ ìjìnlẹ̀ èrò, ìmọ̀ ẹwà àti iṣẹ́ ọnà. Ọ̀kan lára àwọn ẹ̀yà wọ̀nyí ni wọ́n ka lítíréṣọ̀ sí bí wọn ṣe jẹ́ pàtàkì náà ní lítíréṣọ̀ jẹ́ pàtàkì láwùjọ. Ó tẹ̀ síwájú ó ní:

> Lítíréṣọ̀ jẹ́ aṣojú ẹgbẹ́ kan láwùjọ ohun tí a bá ń kà nínú lítíréṣọ̀ èròńgbà àwọn ẹgbẹ́ tí ń gàbalé àwùjọ lórí ni. Ohun èlò sí ló jẹ́ fún àwọn aláṣẹ láti jẹ́ kí ipò wọn ó dúró ṣinṣin, kí ó má bà á sọnù lọ́wọ́ wọn.

Dolbeare nínú Adéọ̀sun (2005, o.i.39-41) sọ pé èrò Karl Marx àti àwọn ẹlẹgbẹ́ rẹ̀ ni pé tí a bá ń fẹ́ kí àwùjọ yípadà kúrò nínú ètò ọrọ̀-ajé 'èmí jù ọ́, ìwọ ò jù mí', kí àwọn mẹ̀kúnnù sì gba ara wọn lọ́wọ́ àwọn akóniṣiṣẹ́, a gbọ́dọ̀ rí àkójọpọ̀ àwọn ènìyàn kan bí ó ti wù kí wọ́n kéré ni iye tó láti jà fún irú àyípadà bẹ́ẹ̀. Nínú iṣẹ́ rẹ̀ yìí kan náà ni Dolbeare sọ pé:

> There must be in effect little microcosm of a new society growing amidst the old. Small groups of people would act on it so as to change it in the direction of the new and beẹome different people (p.193)
>
> (A gbọ́dọ̀ rí bí ó ti wù kí ó kéré tó, àwùjọ tuntun láti inú ti àtijọ́. Ìwọ̀n ba àwọn èèyàn yìí yóò ṣiṣẹ́ lórí bí àwùjọ yóò ṣe yípadà sí dáradára, tí àwọn náà yóò sì yípadà di ènìyàn ọ̀tọ̀)

Adéọ̀sun ní kókó ohun tí Dolbeare ń wí ni pé, tí àwọn ènìyàn àwùjọ bá fẹ́ rí ìyípadà rere, ó di dandan fún wọn láti dìde fún ìjìjàgbara, bí ó ti wù kí àwùjọ kéré tàbí tóbi tó, àwọn ènìyàn ibẹ́ gbọ́dọ̀ gba ara àwọn kalẹ̀ fúnrarawọn lọ́wọ́ ìjọba arẹ́nijẹ tàbí amúnisìn nípa ìjìjàgbara tàbí aáwọ̀.

Ọ̀pẹ̀fèyítìmí (1997, o.i.48) sọ pé:

> Àkíyèsí kan pàtàkì tí ó ń ṣe ìdènà fún àwọn ènìyàn lópòópónà ọ̀rọ̀ ìjàjààgbara yìí ni ọ̀rọ̀ nípa ẹ̀sìn. Ẹ̀sìn àti ìmọ̀ tó rọ̀ mọ́ ọn jẹ́ ọ̀tá ìlọsíwájú fún mẹ̀kúnnù. Ẹ̀sìn ń fi kọ́ wa pé kí á gba kádàrá. B'_lọ́run ti dáyé ni pé kí àwọn kan máà jẹ gàba lórí àwọn ẹ̀dá mìíràn. Àti pàápàá àwọn olówó ló layé yìí, ṣùgbọ́n mẹ̀kúnnù ló lọ̀run. Níwọ̀n ìgbà tó sì jẹ́ pé ayé lọjà, ọ̀run nilé, ká fi olúkùlùkù sílẹ̀ sí ààyè àti ipò rẹ̀, Olúwa ló mẹ́jọ́ọ̀ dá.

Adéyẹmí (2006, o.i.37) ní irú èrò asọni-dẹdun-arinlẹ̀ yìí ni tíọ́rì Máàsì lòdì sí, ó sì gbà pé àwọn mẹ̀kúnnù fúnrawọn ni wọ́n lè gba ara wọn sílẹ̀ lọ́wọ́ arẹ́nijẹ àti amúnisìn tí wọ́n jẹ gàba nípa ọrọ̀-ajé àti ìṣèlú lé àwọn ènìyàn lórí. Adéyẹmí (2006) ní Karl Marx àti Engel kò kanlẹ̀ gbé tíọ́rì yìí kalẹ̀ fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ lítíréṣọ̀, wọn kò tilẹ̀ pè é ní tíọ́rì fún lítíréṣọ̀. Ìdí nìyí tí ó fi sọ pé:

> Àwọn ọmọlẹ́yìn Karl Marx àti Engel ló ra tíọ́rì náà bọ lítíréṣọ̀ lọ́rùn nípa ìdí èyí ẹnu wọn ò kò lórí bí ó ṣe yẹ kí wọ́n lo tíọ́rì náà fún ìtúpalẹ̀ iṣẹ́ lítíréṣọ̀. Ó ní àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì yìí pín sí ọ̀nà méjì. Àwọn ìsọ̀rí kìíní gbà pé ìbáṣepọ̀ tó gbórín wà láàárín iṣẹ́ lítíréṣọ̀ àti ètò ọrọ̀-ajé àti pé ètò ọrọ̀-ajé tó bá wà lóde ni yóò sọ irú lítíréṣọ̀ tí àwùjọ máa ní. Ní ìdàkejì, àwọn mìíràn bí i Duvignaud (1972) gbà pé atúnniro bí agogo ni lítíréṣọ̀ jẹ́, ó sì lè yí ìpinnu àwọn èèyàn àwùjọ padà. Àwọn ìsọ̀rí méjèèjì yìí ló gbà pé àjọṣepọ̀ tún wà láàárín iṣẹ́ lítíréṣọ̀ àti èrò báyéṣerí. Ó ni ajolórí iṣẹ́ ti ìtúpalẹ̀ tí ó tẹ̀lé ìlànà Karl Marx àti èrò ń ṣe ni láti fi orí lítíréṣọ̀ sọ èrò báyéṣerí (p. 37).

## Àhunpọ̀ Ìtàn Ìwé Ìtàn Àròsọ *Kọ Sọ́rọ̀*

Ní abala yìí, àhunpọ̀ ìtàn ìwé Ìtàn Àròsọ *Kọ Sọ́rọ̀* tí a yẹ̀wò ni a ó ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀. Fún ìdí èyí, tí a bá ń sọ̀rọ̀ nípa àhunpọ̀ ìtàn, à ń sọ̀rọ̀ nípa ọ̀nà, àti ètò tí òǹkọ̀wé fi ṣe àfihàn àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìwé rẹ̀. A lè fi gbogbo ẹnu sọ ọ́ pé àwùjọ ilẹ̀ Nàìjíríà ló bi ìwé ìtàn àròsọ *Kọ Sọ́rọ̀*, nípa wíwó àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ inú ìwé náà lẹ́yọ̀-kọ̀ọ̀kan, a lè fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn ìṣẹ̀lẹ̀ ètò ìṣèjọba tàbí ìṣèlú orílẹ̀-èdè Nàìjíríà ni Layọ̀ Ògúnlọlá fi ọgbọ́n àtinúdá hun pọ̀ sí inú ìwé rẹ̀ tí ó pè ní *Kọ Sọ́rọ̀*.

Ọdún 2014 ni wọ́n gbé ìwé ìtàn àròsọ *Kọ Sọ́rọ̀* jáde. Ilé iṣẹ́ ìtẹ̀wé Chridamel Publishing House ní ìlú Ìlọrin ló tẹ̀ ẹ́ jáde. Àwòrán àwọn ọ̀dọ́ ìlú àti àwọn òṣìṣẹ́ tí à ń pọ́n lójú tí wọ́n sì ń fi ẹ̀hónú hàn ni wọ́n yà sí ẹ̀yìn ìwé náà. Ojú ìwé méjìlélàádọ́rin ni gbogbo ìwé náà. Àpapọ̀ orí nínú ìwé ìtàn àròsọ yìí jẹ́ mẹ́rìndínlógún. Àhunpọ̀ ìtàn náà lọ tààrà, ìlú Ayédọgbọ́n ni Ìbùdó ìtàn, ibẹ̀ ni ìtàn náà ti ṣẹlẹ̀, ibẹ̀ ni ìtàn náà sì parí sí. Àfihàn ìwà ìbàjẹ́, ìrẹ́nijẹ àti ìmúnisìn lásìkò ìjọba alágbádá láti ọdọ̀ àwọn aláṣẹ sí àwọn òṣìṣẹ́ ni òǹkọ̀wé hunpọ̀ tó sì di odidi. Gbogbo ìṣẹ̀lẹ̀ ilẹ̀ Nàìjíríà lásìkò ìjọba alágbádá tí àwọn olórí ń rẹ àwọn ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ jẹ ni òýkọ̀wé hunpọ̀ sínú iṣẹ́ ọnà rẹ̀.

Ní orí kìíní ìwé náà, òǹkọ̀wé ṣe àlàyé onírúurú àwọn àìṣedéédéé, èyí tí ó gbilẹ̀ ní orílẹ̀ èdè Ayédọgbọ́n. òǹkọ̀wé jẹ́ kí á mọ̀ pé àwọn ilé iṣẹ́ ọba ti dẹnu kọlẹ̀, owó oṣù àti àjẹmọ́nú àwọn òṣìṣẹ́ kò lọ déédé, onírúurú ìwà ìbàjẹ́, ìrẹ́jẹ àti ìmúnisìn ló gbòde ní orílẹ̀ èdè Ayédọgbọ́n. Ọ̀rọ̀ ìpolongo ìdìbò ni òǹkọ̀wé fi síde orí kìíní ìwé rẹ̀. Orísìí ẹgbẹ́ òṣèlú mẹ́ta ní òǹkọ̀wé dárúkọ, àwọn ni ẹgbẹ́ òṣèlú Máyéró, ẹgbẹ́ òṣèlú Dáyélu àti ẹgbẹ́ òṣèlú Máyégún; olóyè Adérójú ni wọ́n fà kalẹ̀ fún ẹgbẹ́ òṣèlú Máyéró, wọ́n fa ọ̀mọ̀wé Olúfúnmiláyọ̀ Ọmọbọ́lánlé Kalẹ̀ fún ẹgbẹ́ òṣèlú Dáyélu, nígbà tí wọ́n fa ọ̀gbẹ́ni Adáramájà kalẹ̀ fún ẹgbẹ́ òṣèlú Máyégún. Pápá ìṣeréńlá ti ìjọba àpapọ̀ tí ó wà ni Jógunómí ni ìlú Ayédọgbọ́n ni àwọn àjọ elétò ìdìbò ti sètò ìpolongo ìtagbangba fún àwọn olùdìje mẹ́tẹ̀ẹ̀ta.

Àfihàn ìpolongo ibò bònkẹ́lẹ́ ni a rí ní orí kejì ìwé yìí, tí àwọn ẹgbẹ́ òṣèlú ń pín owó, aṣọ, óúnjẹ àti ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ alágbèéká. Olóyè Adérójú ti ẹgbẹ́ Máyéró rán àwọn Mínísítà àti àwọn lọ́gàálọ́gàá lẹ́nu iṣẹ́ ọba padà sí àdúgbò wọn, o pàṣẹ fún wọn kí wọ́n rí i pé wọ́n gba agbègbè wọn fún òun. Ètò ìdìdò tún wáye ní orí yìí. Ọjọ́ kẹta ni èsì gbogbo ibò ti wọ́n dì tó jáde tán. Alága ètò ìdìbò ilẹ̀ náà, ọ̀gbẹ́ni Kásúmù Ayélabówó, ló kéde ọ̀mọ̀wé Olúfúnmiláyọ̀ gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó jáwé olúborí nínú ètò ìdìbò náà, tí ìbúra sì wáyé, lẹ́yìn ìbúra, ààrẹ titun kéde orúkọ àwọn alábàáṣiṣẹ́pọ̀ rẹ̀. Lẹ́yìn ìyannisípò, àwọn òṣìṣẹ́ ọba ń gbèrò ìyanṣẹ́lódì látàrí ẹ̀kúnwó owó oṣù tuntun pẹ̀lú àjẹmọ́nú tí wọ́n ti ń bèèrè fún láti ọjọ́ pípẹ́ wá. Ṣé bí a ṣe ń yọ́ọ́só ni à ń yọ́ọ́gbọ́, èròngbà àwọn òṣìṣẹ́ ta sí etí ìjọba. Wọ́n sì pe olórí àwọn òṣìṣẹ́ ọba, ọ̀gbẹ́ni Dáraníjọ sí ìpàdé, kí ó bá àwọn òṣìṣẹ́ sọ̀rọ̀, kí wọ́n so ìyanṣẹ́lódì rọ̀ ná.

Ọ̀rọ̀ ìpàdé ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ tí ó fẹ́ wáyé. Ọ̀gbẹ́ni Badmus tí ó jẹ́ akọ̀wé ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ ọba lápapọ̀ ló pe ìpàdé náà. Gbogbo olóyè ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ pẹ̀lú aṣojú méjì mìíràn àti aṣojú kan láti olú ilé iṣẹ́ ìjọba àpapọ̀ ló pèsẹ̀ síbi ìpàdé ọ̀hún. Ìpàdé gbogbogbò wáyé, pápá ìṣere Jógunómí kò gbèrò lọ́jọ́ tí à ń wí yìí. Nínú ìpàdé náà, Alàgbà Marvelous bá ìpàdé sọ̀rọ̀, ó jábọ̀ àbájáde ìpàdé tí àwọn ìgbìmọ̀ ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ àti àwọn lọ̀gálọ́gàá lẹ́nu iṣẹ́ ọba ṣe fún gbogbo ọmọ ẹgbẹ́. Ó ní ìgbìmọ̀ ẹgbẹ́ sì ti pinnu láti fún ìjọba ní àyè díẹ̀ sí i. Láríjà ìpàdé wọn náà ni pé, kí àwọn òṣìṣẹ́ ṣe sùúrù fún ìjọba àpapọ̀. Ọ̀rọ̀ ìyanṣẹ́lódì àwọn òṣìṣẹ́ ọba ló gbòde kan ní orí kẹfà. Àwọn ilé iṣẹ́ ìròyìn lọ́kan-ò-jọ̀kan ń bu ẹnu àtẹ́ lu ìhà kò-kàn-mí tí àwọn aláṣẹ kọ sí ọ̀rọ̀ náà. Bákan náà ní ìdí ayò, ní ilé ọtí àti níbi ìgbafẹ́ gbogbo, wọ́n kò rí ọ̀rọ̀ mìíràn sọ, àfi ọ̀rọ̀ ìdaṣẹ́ sílẹ̀ yìí. Ọ̀rọ̀ ìyanṣẹ́lódì di ohun tí àwọn ọ̀mùtí fi ń sàwàdà ní ilé ọtí.

Ní orí keje ní akọ̀wé ìjọba àpapọ̀ ti kéde ìpinnu ìjọba fáyé gbọ́ pé àwọn aláṣẹ tí gbáradì láti fi ìyà jẹ àwọn òṣìṣẹ́. Síbẹ̀ àwọn adarí ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ ọba fàáké kọ́rí pé ọmọ ẹgbẹ́ kankan kò gbọdọ̀ padà sẹ́nu iṣẹ́. Wọ́n tún gbé ìjọba lọ sí ilé ẹjọ́. Wọ́n sì fi ẹ̀sùn mẹ́ta ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ kan ìjọba. Ìjọba náà pe àwọn olórí òṣìṣẹ́ ọbalẹ́jọ́ sí ilé ẹjọ́ kan náà. Ẹ̀sùn tí wọ́n kà sí wọn lẹ́sẹ̀ fẹ́rẹ̀ tó ọgbọ̀n.

Ní orí kẹjọ, ìgbẹ́jọ́ kò lè wáyé lọ́jọ́ àkọ́kọ́ nítorí pé mímú tí wọ́n mú Dáraníjọ tì mọ́lé ti dá yánpọnyánrin sílẹ̀ láàrin ìlú. Ààrẹ pe ìpàdé pàjáwìrì àwọn aláṣẹ ìjọba. Ààrẹ korò ojú sí àwọn ọlọ́pàá pé wọn kò rí àwọn ọdàlúrú ṣe ní nnkankan. Lẹ́yìn-ò-rẹyìn, amòfin Oyíndàmọ́lá ni ọ̀nà àbáyọ àkọ́kọ́ ní kí ìjọba tú ẹni tó wà nígbèkùn ọlọ́pàá sílẹ̀. Báyìí ni wọ́n tú Dáranijọ sílẹ̀. Tí òǹkọ̀wé ṣe àfihàn ilé ẹjọ́, lẹ́yìn tí agbẹjọ́rò òṣìṣẹ́ parí àwíjàre rẹ̀ ní ilé ẹjọ́, ọ̀mọ̀wé Oyíndàmọ́lá tó jẹ́ agbẹjọrò ti ìjọba náà mẹ́nu lé àwíjàre tirẹ̀. Ṣùgbọ́n ìdájọ́ kò le wáyé lọ́jọ́ yìí rárá, adájọ́ sún ìdájọ́ rẹ̀ sí ọjọ́ mẹ́ẹ̀ẹ́dógún.

Òǹkọ̀wé tún gbé ọkàn àwọn òǹkàwé rẹ̀ lọ sí ilé ayò ní orí kẹwàá. Ọ̀rọ̀ tí ó ń ṣẹlẹ̀ láarin ìjọba àti àwọn òṣìṣẹ́ ni wọ́n fi ń ṣẹ̀fẹ̀. Lẹ́yìn èyí ni à tún rí gbọ̀ngàn ilé ẹjọ́, níbi tí adájó ti pàṣẹ kí àwọn òṣìṣẹ́ padà sẹnu iṣẹ́, kí ìjọba náà sì gbáradì láti san gbogbo owó oṣù àti àjẹmọ́nú àwọn òṣìṣẹ́. Àwọn òṣìṣẹ́ ọba padà sí ẹnu iṣẹ́ wọn ní ọjọ́ Ajé tí ó tẹ̀lé ọjọ́ ìdájọ́. Ààrẹ yan ìgbìmọ̀ ẹléni-mẹ́fà láti ṣe àgbéyẹ̀wò ọ̀rọ̀ adájọ́ náà, kí wọ́n sì gba ìjọba ní ìmọ̀ràn. Mínísítà ètò ìsúná ni tí àwọn bá fi le sanowó yìí, ìjọba kò ní lè san ẹ̀kúnwó owó oṣù tí wọ́n ń gbèrò fún àwọn aṣòfin àti Gómìnà. Lẹ́yìn oṣù méjì tí ìjọba kò ṣe nǹkankan, ni àwọn òṣìṣẹ́ tún gùnlé ìyanṣẹ́lódìní pẹrẹu.

Ọ̀rọ̀ ìdájọ́ ẹjọ́ ẹlẹ́ẹ̀kejì tí àwọn òṣìṣẹ́ pè ló sodo sí orí kejìlá. Nínú ìdájọ rẹ̀, Adájọ́ Ọmọnísì ní ilé ẹjọ́ kò rí aburú kan tí àwọn òṣìṣẹ́ ọba ṣe nítorí pé bákan náà ni gbogbo wa rí lábẹ́ òfin. Ilé ẹjọ́ faramọ́ ìdájọ́ àkọ́kọ́, ó sì fi òfin de àwọn aláṣẹ láti má ṣe àfikún owó oṣù ẹnikẹ́ni títí wọn yóò fi yanjú gbèsè tó wà nílẹ̀. Ilé ẹjọ́ rọ àwọn òṣìṣẹ́ ọba láti padà sẹ́nu iṣẹ́ wọn láìfi àkókò ṣòfò. Àwọn òṣìṣẹ́ padà sẹ́nu iṣẹ́ gẹ́gẹ́ bí adájọ́ ṣe pa á láṣẹ fún wọn. Àwọn aláṣẹ kò tẹ̀lé ìdájọ́, wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí i fún àwọn èniyàn ní ìwé ìdádúró lẹ́nu iṣẹ́. Ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ náà faraya, àwọn aláṣẹ náà fi ààké kọ́rí. Ọjọ́ kẹta ni rògbòdìyàn bẹ̀rẹ̀. Àwọn ọlọ́pàá ń ju àdó atanilójú sáàrin àwọn èrò, síbẹ̀ wọn kò bìkítà.

Ohun gbogbo dúró sí ojú kan. Ètò ọrọ̀ ajé ìlú Ayédọgbọ́n ń burú sí i, bẹ́ẹ̀ sì ni ara ń ni ará ìlú. Nígbà tí ọ̀rọ̀ náà kò fẹ́ lójútùú mọ́, àwọn ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ tọ àwọn ọba lọ. Wọ́n fi ẹ̀sùn olè, ànìkanjọpọ́n, ìmọtara-ẹni-nìkan, jẹgúdújẹrá kan àwọn aṣòfin. Ìgbìmọ̀ àwọn lọ́balọ́ba yan aṣojú mẹ́rin láti lọ rí àwọn aṣòfin, ṣùgbọ́n àwọn aṣòfin ní ẹnu àgbà ń rùn. Àwọn òṣìṣẹ́ sọ ọ̀rọ̀ náà di ìjà ìgboro. Báyìí ni aáwọ̀ bẹ̀rẹ̀, àwọn ẹgbẹ́ obìnrin ló ṣáájú. Ọwọ́ àwọn afẹ̀hónúhàn sì tẹ mẹ́rin nínú àwọn aṣòfin. Ààrẹ ṣe ìpàdé bòǹkẹ́lẹ́ pẹ̀lú àwọn aṣòfin. Àwọn aṣòfin rọ Ààrẹ kí ó wá ọ̀nà àbáyọ mìíràn sí ọ̀rọ̀ náà. Ààrẹ bá ìgbìmọ̀ lọ́balọ́ba ṣe ìpàdé pàjáwìrì. Nínú ìpàdé náà, ó rọ àwọn lọ́balọ́ba láti fi ọwọ wọ́nú lórí abùkù olóroǹbó tí àwọn aṣòfin fi kàn wọ́n sẹ́yìn, kí wọn jọ̀wọ́ dá sí ọ̀rọ̀ yìí. Èyí ló ṣe òkùnfà ìpàdé àwọn aláṣẹ ìjọba, àwọn olóyè ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́, aṣojú àwọn ọba àti àwọn aṣòfin. Ìbànújẹ́ dorí àgbà kodò, àwọn aṣòfin kò rí ọ̀rọ̀ sọ. Ààrẹ ṣè lérí láti san owó àwọn òṣìṣẹ́ ní kíákíá. Àwọn orí adé pàrọwà sí àwọn òṣìṣẹ́ ọba, àwọn òṣìṣẹ́ náà sì ṣèlérí láti tú àwọn tó wà ní ìgbèkùn sílẹ̀.

Ní orí kẹrìndínlógún tí ó parí ìwé ìtàn àròsọ yìí, ìpàdé tí abẹnugan ilé ìgbìmọ̀ aṣòfin pè àti ìdọ́ọ̀wọ́ ìdùnnú àwọn ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ wáyé. Aṣojú àwọn aṣòfin jábọ̀ ìpàdé fún wọn, ó fi ẹ̀dà ìwé àdéhùn tí wọ́n tọwọ́ bọ̀ hàn wọ́n. Ọjọ́ ajé ni àwọn òṣìṣẹ́ ọba ṣe ìpàdé tiwọn. Ìdùnnú ṣubú layọ̀ fún gbogbo wọn lọ́jọ́ náà. Ọjọ́ kejì ni wọ́n tó tú àwọn tó wà nígbèkùn sílẹ̀. Ìjọba pàápàá kéde pé aáwọ̀ tí ó wà láàrin òun àti ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ ti dópin, wọ́n sì rọ àwọn òṣìṣẹ́ kí wọ́n padà ṣẹ́nu iṣẹ́ nítorí pé ìjọba ti gbà láti san gbogbo gbèsè tí wọ́n jẹ àwọn òṣìṣẹ́ ọba láìfi ìyà jẹ ẹnikẹ́ni.

**Ìlò Èdè Inú Ìwé Ìtàn Àròsọ *Kò Sọ́rọ̀*.**

Èdè ni ọkọ̀ tí a fi wa lítíréṣọ̀ wá sáyé, òun tún ni ẹsin tí lítíréṣọ̀ gùnlé. Tí kò bá sí èdè kò ní sí lítíréṣọ̀. Bí ìgbà tí èékánná lẹ̀mọ́ ìka ni lítíréṣọ̀ àti èdè jẹ́. Abálájọ tí Ọlábimtán nínú Adéọ̀sun (2005, o.i.76) fi sọ pé:

> Gẹ́gẹ́ bí ọkọ̀ àti àdá ti rí lọ́wọ́ àgbẹ̀, tí kálámù sì rí lọ́wọ́ alákọ̀wé bẹ́ẹ̀ ni èdè lọ́wọ́ akéwì. Kò sí itú tí akéwì kò lè fi èdè pa.

Ẹ̀wẹ̀, Ọ̀pẹ́fèyítìmí (1997, o.i.65) náà kín èrò yìí lẹ́yìn nígbà tí ó sọ pé “èdè ni irinṣẹ́ àmúlò fún iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀. Èdè kọ̀ọ̀kan ló sì ní ọ̀nà tó ń gbà ṣe ẹwà” Ó tún fi kún un pé oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni a ń gbà lo èdè, oríṣìíríṣìí nǹkan ni a sì ń lo èdè fún. Nínú iṣẹ́ aláwòmọ́ lítíréṣọ̀ ìlò èdè ṣe pàtàkì, bí òýkàwé bá gbádùn iṣẹ́ ọnà kan, ìlò èdè tí òǹkọ̀wé lò ló mú un gbádùn irú iṣẹ́ bẹ́ẹ̀. Àwọn ìlò èdè tí a le bá pàdé nínú iṣẹ́ lítíréṣọ̀ ni òwe, àfiwé tààrà, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́, ìfohùnpènìyàn, ìfènìyànpohùn, ìfọ̀rọ̀dárà, àwítúnwí, àkànlò èdè àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ.

Ìlò èdè inú ìwé àyànlò gbóúnjẹ fẹ́gbẹ́, ó sì tún gbàwo bọ̀. Òǹkọ̀wé fi ara rẹ̀ hàn gẹ́gẹ́ bí ẹni tí ó ní ìmọ̀ ìmẹ̀sọ ọ̀rọ̀ nípa lílo ìjìnlẹ̀ èdè láti fi ṣe àgbékalẹ̀ ìtàn rẹ̀, Ó tún fi ara rẹ̀ hàn bí ẹni tí ó ni ìmọ̀ àṣà àti ìṣe Yorùbá dáradára nípa ṣíṣe àmúlò èròjà àṣà Yorùbá nínú ìlò èdè rẹ̀. Ó ṣe àmúlò àwọn lítíréṣọ̀ alohún pẹ̀lú èròngbà àti fi ìlò èdè sọ fún àwùjọ bí àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá ti jinlẹ̀ tó. Láti jẹ́ kí a mọ̀ pé èdè kò dúró sí ojú kan Òǹkọ̀wé ṣe àmúlò àyálò èdè pààpàà jùlọ láti inú èdè Gẹ̀ẹ́sì.

Ní ilẹ̀ tó mọ́ lónìí, bí a bá fẹ́ mọ ọ̀nà ìsọwọ́lò-èdè òǹkọ̀wé tàbí akéwì kan, a ó fi ojú ìmọ̀ lìngúísítíìkì àti lítíréṣọ̀ wo iṣẹ́ náà (Adéọ̀sun, 2005, o.i.77). Ọ̀nà kejì (Lítíréṣọ̀) tí ó jẹ́ ọ̀kan lára ọ̀nà méjèèjì yìí ni a fi ṣe ìtupalẹ̀ ìlò èdè Layọ̀ Ògúnlọlá ní ìbámu pẹ̀lú tíọ́rì àmúlò. Ní abala yìí, kìí ṣe kí á wo ìlò èdè sákálá ló jẹ wá lógún, bí kò ṣe pé kí á wo ìlò èdè bí ó ṣe jẹ mọ́ ìjìjàgbara àti irú ìpèdé tí Òǹkọ̀wé fi sí ẹnu àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ tí wọ́n jẹ́ àkùkọ gàgàrà (irú èyí tí Karl Marx ń pè fún). Nítorí pé àwọn agbátẹ̀rù tíọ́rì Karl Marx kò ní ìgbàgbọ́ nínú mímú sùúrù, iforítì, àti ìfàyàrán ìṣòro, èdè kan tí wọ́n ní ìgbàgbọ́ pé àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisìn gbọ́ náà ni aáwọ̀, ìfẹ̀hónúhàn àti ìjìjàgbara.

Ní ìpele lítíréṣọ̀, òǹkọ̀wé lo àwọn ọnà èdè láti fi èdè àwọn afẹ̀hónúhàn àti amúnisìn han àwùjọ. Ní àkọ́kọ́, nínú ètò ìsèjoba olókoòwò aládàánlá gbogbo àwọn ènìyàn lo máa ń lépa àtiwà nípò ìsẹ̀lú. Nígbà ti ètò ìdìbò wáyé, tí olóyè Adérójú pàdánù nínú ètò ìdìbò náà, tí àwọn mìíràn nínú àwọn olùdíje náà faraya. Àwọn tó pàdánù nínú ètò ìdìbò náà ti lérò pé ìyànjẹ, ẹ̀tàn àti ìrẹ́nijẹ ti wọ èsì ìdìbò náà. òǹkọ̀wé lo àkànlo èdè àti òwe láti fi ṣàlàyé pé inú àwọn olùdíje ti ó pàdánù nínú ètò ìdìbó ko dun sí bí èsì ìbò náà ṣe lọ. O ní:

> Síbẹ̀ àwọn kan fi ààké kórí pé àwọn kò ní gbà. Wọn ní kàkà kí àkèrè máà dunbẹ̀, tápa titan rẹ̀ ni yóò rún síí. Kàkà kí eku má jẹ ṣẹ̀ṣẹ́ yóò fi ṣe àwàdànù ni (o.i.10)

Èyí fihàn pé gbogbo àwọn olósèlú lo máa ń lépa àti wà ni igbonnù ètò ìsèlú, lónà àti máà pọ́n mùdùnmúdùn orílẹ̀ èdè la. Àtipé ohunkohun tí ó ba gba ni àwọn yóò fún láti máà pín nínú ọrọ̀ orílẹ̀ èdè, ti wọn yóò fi máà rẹ àwọn mẹ̀kúnnù jẹ, tàbí mu wọn sìn bí ẹran àgbò.

Ìlò èdè òǹkọ̀wé pẹ̀lú Ààrẹ Adérójú fihàn pé àwọn arẹnijẹ a máa jayé ìjẹkújẹ, àtipe ti ipò àṣẹ bá tí bọ́ sí ọwọ́ àwọn arẹnijẹ, wọ́n ti gbàgbọ́ pé ko sí ẹni tí ó le yẹwọ́n lọ́wọ́ wò. Ìdí nìyí ti òǹkọ̀wé ṣe lo àkànlò èdè àti òwe láti fi ṣàkàwé ìhùwàsí àwọn olósèlú arẹ́nijẹ-múnisìn. Ó ní:

> ... Dípò bẹ́ẹ̀, ó ń jaye ọba, ayé fà mí létè kí n tútọ́. Adérójú ń yọ ayọ
> “Ìyàá mi ni wọ́n rà wọn ò rà mí” ó ní: a ti tòjé bolórìṣà lọ́wọ́ ó ku
> bàbá ẹni ti yóò bọ o (o.i.1).

Àyọlò yìí tún fi yé pé, àwọn olóṣèlú arẹ́nijẹ rí ipò àṣẹ tàbí ipò òṣèlú bíi àbákú laṣọ ahun. Oníríurú ilò èdè ló wáyé láti fi bí àwọn arẹ́nijẹ ṣe ń rẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ jẹ, bákan náà bí àwọn òṣìṣẹ́ ṣe gba ara wọn kalẹ̀. Gẹ́gẹ́ bi a ti mọ̀ pé èdè líle ni èdè àwọn ajijagbara. Karl Marx àti àwọn agbátẹ̀rù rẹ̀ kò ní ìgbàgbọ́ nínú ìwáásù ẹ máa mú sùúrù tàbí ìforítì. Ohun ti ó jẹ Karl Marx lógún ni ìgbéṣẹ̀ kíákíá, ìjìjàgbara tàbí aáwọ̀ nígbà tí àwọn ènìyàn bá tí rí ipa ìrẹ́jẹ tàbí ìmúnisìn. Nínú ìwé ìtàn àròsọ *Kò Sọ́rọ̀*. òǹkọ̀wé fi èdè àwọn olóṣèlú arẹ́nijẹ hàn lọ́nà tí ó bí àwọn òṣìṣẹ́ nínú, tí ó si mú àwọn òṣìṣẹ́ gùnlé ìyanṣẹ́lódì àti ìjìjàgbara tàbí aáwọ̀. Nígbà tí ìgboro dàrú, tí àwọn àjìjàgbara dá aáwọ̀ sílẹ̀, inú àwọn aṣòfin orílẹ̀ èdè Ayédọgbọ́n kò dùn. Ọ̀kan lára àwọn aṣòfin ní òǹkọ̀wé fi àkànlò èdè àti òwe sí lẹnu. Ó ní:

> Wọ́n ní bí ẹnikẹ́ni nínú àwọn òṣìṣẹ́ ọba bá *gbémú* nígbèékúgbèé gígé ni wọn yóò gé imú onítọ̀hún. Nítorí ilà ò gbọdọ̀ ga ju olóko lọ (o.i.61).

Èdè àwọn arẹ́nijẹ ni èyí, ní èyí tí ó múnú bi àwọn òṣìṣẹ́. Wọn gbà pé àwọn làwọ́n wà nípò aṣẹ, àwọn ni wọ́n sì gbá àwọn òṣìṣẹ́ síṣẹ́, fún ìdí èyí, bí ó ba ṣe wu ìjọba ló ṣe le ṣe àwọn òṣìṣẹ́. Àwọn arẹ́nijẹ ri àwọn òṣìṣẹ́ bí ẹrú. Àtipé ibi tí ó ba wu ẹ̀fúùfù lẹ̀lẹ̀ ìjọba ló le darí ìgbẹ́ àwọn òṣìṣẹ́ sí. Àwọn arẹ́nijẹ gbà pé àwọn láṣẹ láti ṣe èyíkéyìí nínú àwọn òṣìṣẹ́ bó bá ṣe wùwọ́n. Ìdí nìyí tí Àarẹ fi sọ̀rọ̀ pé ilá tó ba ga ju olóko lọ a bẹ́ ẹ lórí sọnù (o.i.34). Ìlò èdè ẹnu Sínétọ̀ Adéọ̀sun fi àwọn olóṣèlú arẹ́nijẹ hàn bíi ìkà àti alàìláàánú ẹ̀dá. Ó ní:

> Kín ni àwọn agbófinró wà fún? Ẹnikẹ́ni tó bá gbèrò láti da ìlú yìí rú. Kí wọ́n ṣe é bí ọṣẹ ṣe é ṣojú (o.i.60).

Ìlò èdè àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisìn ní èyí. ìlò èdè ìjẹgàbalé. Ní ojú àwọn olóṣèlú arẹ́nijẹ, bó tilẹ̀ wù kí irungbọn alágbàṣe gùn tó, ẹni ti ó gbé oko fún un lọ̀gá rẹ (o.i.40). Ọ̀pọ̀ ló gbà pé aṣeju àwọn arẹ́nijẹ pọ̀ àti pé àlàáfíà mẹ̀kúnnù kò jẹ́ wọ́n lógún. Ní ojú àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisìn ẹni àmọ̀rí ìbáà ku ni (o.i.55). Àwọn ìlò èdè wọ̀nyí ń ṣè àfihàn àwọn arẹ́nijẹ gẹ́gẹ́ bí alàìláàánú àti onímọ-tara-ẹni-nìkan, àwọn tí ó máa ń lu ìlù bámúbámú ni mo yó, nkò mọ̀ pé ebi ń pa ọmọ ẹnìkọ̀ọ̀kan. Èrò ọkàn ọ̀mọ̀wé Ajibọla fi àwọn olóṣèlú hàn bí arẹ́nijẹ àti amúnisìn nígbà tí wọ́n yàn án sí ipò olórí òṣìṣẹ́ ọba ní ìlú Ayédọgbọ́n. Èrò ọkàn rẹ̀ yìí ṣe àfihàn àwọn olóṣèlú bi ọ̀kánjúà àti onímọ tara ẹni nìkan. Ó ní:

> Alákàrà òṣèlú kan, kò sì fẹ́ kí èkejì ó dín (o.i.13).

Ìwà àfèmi-àfèmi ti àwọn olóṣèlú máa ń hù ni èyí. Ìlò èdè yìí fi àwọn olóṣèlú arẹ́nijẹ hàn bí olójúkòkòrò àti wòbìà. Wọn kìí fẹ ri ẹlòmìíràn nínú ètò ìṣèjọba, àwọn tí o ti ń ṣe ètò ìṣàkóso láti ọjọ́ tó ti pé náà ni wọn tún máa ń fẹ́ wà níbẹ̀. Wọ́n ti ka ipò olórí sí oyè ìdílé. Mùdùnmúdùn orílẹ̀ èdè ti rọ̀sọ̀mù síwọn lẹ́nu, wọn kò sí fé kí àwọn mìíràn báwọn pọ́nlá nínú ọrọ̀ orílẹ̀ èdè. Ì lò èdè àwọn ọba alayé sí àwọn aṣòfin àti ìlò èdè àwọn òýtayò fi àwọn aṣòfin han bí arẹ́nijẹ. òǹkọ̀wé ni:

> Àwọn ọba alayé sọ ògúlùtu ọ̀rọ̀ lu àwọn aṣòfin. Kò sí orúkọ tí wọn ó pé wọ́n tán. Ẹnìkan pé wọn ní firí nídìí ọ̀ké, ẹlòmìíràn pè wọn ní Arẹ́nijẹ: Amúnisìn, Agbàlọ́wọ́ọmẹ́ẹ̀rí àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ (o.i.69).

Ní ìdí ayò àwọn kan rí wọ́n bíi:

> ."Gbájúẹ̀" "419" nígbà tí àwọn mìíràn pè wọ́n ní fìrí nídìí ọ̀ké, Agbàlọ́wọ́ọmẹ́ẹ̀rí (o.i.25).

"Fìrí nídìí ọ̀kẹ́" jẹ́ àkànlò èdè. Ìtumọ̀ fìrí nídìí òké ni "olè" òǹkọ̀wé lo àdàpè láti fi ṣàfihàn àwọn arẹ́nijẹ. Ìtumọ "Gbájúẹ̀ àti 419" ní olè, oníjibiti, onímàkàrúrù, alọ́nilọ́wọ́gbà, alọkólóhun ó kígbe, agbàlọ́wọ́ọméẹ̀rí jẹ ẹni tí o tún ń gbà lọ́wọ́ àwọn ti kò ní. Àwọn ìlò èdè yìí ń ṣe àfihàn ìwà àti ìṣesí àwọn olóṣèlú àwùjọ Nàìjíríà, torí pé ti a ba wo ètò ìṣèlú orílẹ̀ èdè Nàìjíríà báyìí, a óò rí pé pẹ̀kípẹ̀kí ni àwọn ìwà ìrẹ́nijẹ àti ìmúnisìn sodo sí àwọn olóṣèlú lára. Àdàpè ni òǹkọ̀wé lò láti fi ṣe àfihàn àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisìn pẹ̀lú àyọlò òkè yìí. Gẹ́gẹ́ bi a ti sọ ṣáájú pé, àwọn agbátẹrù tíọ́rí Karl Marx tako ìwáásù ẹ máa mú sùúrù, ìforítì, ìfaradà, àti ìfàyàrán ìṣòro àti pé àwọn ènìyàn àwùjọ kò gbọ́dọ̀ jẹ́ kí àwọn arẹ́nijẹ tàbí amúnisìn lo ẹ̀sìn, àṣà tàbí ẹ̀kọ́ nípa ìwà ọmọlúàbí láti fi bò wọ́n lójú sí ọ̀nà ìjẹgàba lé wọn lórí (Mannan) nínú (Adéọ̀sun,2005, o.i.42).

Ògúnlọlá ṣe àmúlò àwọn ìpèdè ẹ máa mu sùúrù, ní èyí ti a lérò pe, ó fẹ́ ki àwọn èníyàn àwújọ mọ ìpèdè àwọn arẹ́nijẹ àti amúnìsin, kí wọ́n sì dìde fún ìjìjàgbara irú èyí tí àwọn agbátẹrù tíọ̀rì Karl Marx ń pè fún. Nígbà tí Alàgbà Marvelous jábọ̀ ìpàdé ti àwọn olóyè ẹgbẹ́ ṣe pẹ̀lú Ààrẹ àti àwọn lọ́gàálọ́gàá lẹ́nu iṣẹ́ ọba. Nígbà tí ó ń sọ̀rọ̀, ó ni Ààrẹ sọ pe:

> …ó wa rọ ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ lápapọ láti fọwọ́ wọ́nú kí wọ́n si fi ẹ̀dọ̀ lorí òróòro nítorí pé pẹ̀lẹ̀ ni a fi ń pa àmúkùrù pẹ̀lẹ́. Ènìkan kìí kànjú lá ọbẹ̀ tó gbóná (o.i.20-21).

Ọ̀rọ̀ ẹnu olóòtú ìwé íróyin elétí ọfẹ fi ìlò èdè àwọn arẹ́nijẹ hàn. Ó ní:

> Olóòtú rọ arà ìlú làti fọwọ́sowọ́pọ̀ pẹ̀lú àwọn òṣìṣẹ́ ọba, kí wọn ní ìfaradà títí ìjọba yóò fi wá wọ̀rọ̀kọ̀ fi ṣe àdá lórí ọ̀rọ̀ náà (o.i.25).

Aya Ọládèbó ló tun fi ìlò èdè àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisín hàn níbi ìpàdé gbogbogbòò ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ ọba ní pápá ìṣeré Jógunómí. Ó ní:

> Ṣùgbọ́n òkun kìí hó ruru, kí á tún máa wẹ̀ ẹ́ ruru. pẹ̀lẹ́ la fi ń pa àmúkùrí pẹ̀lẹ́. Ìtí ọ̀gẹ̀dẹ́ ní ọ̀rọ̀ náà kò tó ohun tí à ńlọ àdà fún. Ẹjọ́ ló yé kí á kọ́ kìì ṣe ìjà …… (o.i.21).

Àwọn ìpèdè yìí fihàn pé ìwàásù ẹ máa mu sùúru, ìfaradà, ìforítì ló jẹ́ àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisín lógún. Ìwáásù sùúrù yìí ni wọn ń lò làti fi tan àwọn mẹ̀kúnnù jẹ́, títí wọn yóò fi fún gbogbo wàrà orílẹ̀ èdè gbẹ, tí ọrọ̀ orílẹ̀ èdè yóò sí jẹ́ tiwọn níkan. Ògúnlọlá lo àkànló èdè àti òwe Yorùbá làti fi ìpèdè tàbí ìlò èdè àwọn arẹ́nijẹ hàn. Àwọn ìlò èdè wọ̀nyí tako ìlànà àwọn agbátẹ̀rù Karl Marx. Ohun tí àwọn agbátẹ̀rú Karl Marx ń wí ni pé tí àwọn ìlò èdè bá wọ̀nyí bá tí ń yọjú kí àwọn mẹ̀kúnnù tètè gbé ìgbésẹ̀ kíákíá, kí wọ́n sí fi ìjìjàgbara tàbí aáwọ̀ gba ara wọn kalẹ̀, nítorí pé n ò le wá kú kìí róyè ilé bàbá rẹ̀ jẹ.

Gẹ́gẹ́ bí àwọn agbátẹ̀rù tíọ̀rì Karl Marx ṣe sọ, àwọn wọ̀nyí gbà pé èdè kan tí àwọn arẹ́nijẹ àti amùnìsin gbọ́ náa ni ìjìjagbara. Onírúurú ìlò èdè ni àwọn ajíjàgbara ṣe àmúlò làti fi gba ara wọn kalẹ̀ lọ́wọ́ ìjọba arẹ́nijẹ àti amúnisin. Iyanṣẹ́lódì ni àwọn òṣíṣẹ́ kọ́kọ́ bẹ̀rẹ̀, kí wọ́n tó gùnlé ìjìjàgbara. Àwọn òṣìṣẹ́ rí ìrẹ́nijẹ àti ìmúnisin bi ohun to le sọ ni di ẹdun arinlẹ̀, wọ́n pínnu làti fi òpin sí ìrẹ́jẹ èyí tí ó gbilẹ̀ náà láàrin àwọn aláṣẹ àti òṣìṣẹ́. òǹkọ̀wé lo ọfọ̀ àti òwe làti fihàn àwọn arẹ́nijẹ pé àwọn òṣìṣẹ́ ti ṣetán làti fi ìyansẹ́lódì àti ìjìjàgbara pẹ́ẹ̀ta pẹ̀lú wọ́n. O ní:

> Ṣùgbọ́n kó sí ṣíṣe, ko sí àìse, ìyanṣẹ́lódì gbọ́dọ̀ bẹ̀rẹ̀ nítorí ìràwé kan kìí dájọ́ ilẹ̀ kò sùnkè. Màá foko mi dá ọ̀ná ọjọ́ kan ni à ń kìlọ̀ rẹ̀. Ohun ti a kò bá sí níí gbá lólówó, tàlàkà ni a ti í kọ̀ ọ́ (o.i.26).

Ìlò èdè àwọn ajìjàgbara ni èyí. Àyọlò yìí ń sọ fún àwọn mẹ̀kúnnù pé ìjìjàgbara kì í ṣe ohun tí a máa ń dájọ́ sí, pé ọjọ́ tí a bá rí ibi, ni ibi ń wọlẹ̀, bí bẹ́ẹ̀ kọ́ àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisìn yóò máa tẹ̀síwájú nínú iṣẹ́ ibi ni.

Ìjìjàgbara jẹ Ògúnlọlá lógún dé ibi pé ó lo àtòlé òwe láti fi ìlò èdè àwọn ajìjàgbara hàn. Ó ní:

> Má fi oko mi dáná, ọjọ́ kan làá sòfin rẹ̀. Ẹnu ẹni sì ni a fi í kọ méèjẹ. N ò le wá kú kìí rí oyè ilé bàbá rẹ̀ jẹ. Àìle sọ̀rọ̀ ni ìpìlẹ̀ orí burúkú ( o..i. 72).

Ọ̀gbẹ́ni Adáramájà nínu ètò ìpolongo ìbò náà ṣọ pé:

> Ó tó àkókò wàyí. tí a nílati fi ẹnu ara wa kọ méèjẹ (o.i.4)

òǹkọ̀wé náà ṣàmúló ílò èdè kan náà. Ó ní:

> Àfi kì àwọn òṣìṣẹ́ funra wọn múra làti tu ara wọn sílẹ̀ nítorí ẹnu ẹnu là á fi í kọ méjẹ̀ẹ (o.i. 13).

Ìpè fun ìjìjàgbara ni ìló èdè yìí. Ògúnlọlá ń fẹ́ ki àwọn èniyàn ní àwùjọ mọ̀ pé, àwọn fúnra wọn ni yòó gba ara wọn kalẹ̀ lọ́wọ́ àwọn arẹ́nijẹ, Áńgẹ̀lì kankan kò ní sọ̀kalẹ̀ wá. Àtipé ti wọ́n bà ń bẹ̀ru àtikú tàbí wọ́n ń bẹ̀rù àti fi ijà pẹ́ẹ̀ta, kí wọ́n má retí òmìnira tàbí ìtúsílẹ̀ kankan. Síwájú síi, ó ń fẹ́ kí wọ́n mọ̀ pé, tí wọ́n bá dákẹ́, ti ara wọn yòó bá wọn dákẹ́, ti wọ́n bá káwọ́ gbera inú ìṣẹ́ àti ìyà ni wọn yóò kú sí.

Ògúnlọlá ṣe afihan ìlò èdè àwọn ajìjàgbara lọ́nà ti ó fi tẹ̀lé ìlànà àwọn àgbátẹrù tíọ́rì Karl Marx. Akọ̀wé ìjọba àpapọ̀ ló jẹ́ kí a mọ̀ pé àwọn òṣìṣẹ́ ti fa raya láti gùnlé ìyanṣẹ́lódì àti aàwọ̀. Ó ní

> Ìjọba ti sa gbogbo ipá rẹ̀ làti pàrọwà sí ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ kí wọ́n fọwọ́ wọ́nú ṣùgbọ́n wọ́n fi ààké kọ́rí, wón kó etí ikún sí àrọwà ìjọba. wọ́n ní kàkà kéku má jẹ ṣẹ̀ṣẹ̀, yóò fi ṣe àwàdànù ni (o.i.27).

Nígbà ti àwọn arẹ́nijẹ tún gbìyànjú àti fi ìyà jẹ́ àwọn òṣíṣẹ́ síwájú, lẹ́yìn ìgbà ti wọ́n kò san owó oṣù àti àwọn àjẹmọ́nú wọ́n, wọ́n tún gbé ìgbésẹ̀ lati dá àwọn òṣìṣẹ́ kan dúró lẹnu iṣẹ́. Èyí mú inú bí àwọn ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́. òǹkòwé ní:

> Ìdúró kò sí, bẹ́ẹ̀ ní ìbèrẹ̀ kò sí fẹ́ni tó gbé ọmọ odó mì. Ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ fọnmú, wọ́n tútọ̀ sóké wọ́n fojú gbà á (o.i.57).

Ọ̀rọ̀ ẹnu ọ̀gbẹ́ni Jẹ́ngbáyé ni ilé ọtí "Màmà shop" fi ìlò èdè ajìjàgbara hàn. Ó ní:

> Kín ni wọ́n fẹ́ ṣe fún wa? kín ni à ń se ẹgbẹ́ fún? kò ṣéwu lóko, àfi gììrì àparò. Àwa kìí ṣe ajá tó lé gbó ṣugbọ́n tí kò lè buni san. Ẹ kó ilà kúrò lẹ́kọ, ẹ̀kọ kìí kọlà, ewé ló ń kọlà sára ẹ̀kọ. Bí ikún ló loko, bì pàkúté ni, ó digbà náà (o.i.28-29).

Nínú àyọlò mẹ́ta òke yìí, òǹkọ̀wè ṣe àmùlò àkànlò èdè, òwe, ìbèèrè pèsìjẹ, àfiwé ẹlẹ́lọ̀ọ́ àti pé èdè tí àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisìn gbọ́ náà ni àwọn ẹ̀dá ìtàn ṣàmulò. Ìhùwàsí wọn náà fihàn pé wọn ti ṣetán àti gbé agbada àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisìn kúrò, ìdi níyí ti wọ́n fi faraya. Ìlò èdè yìí fihàn pé ẹgbẹ́ òṣìṣẹ́ ṣetan làti já ara wọn gbà. Bakan náà ló jẹ́ pe àwọn ẹ̀dá ìtàn wọ̀nyí ṣàmúlò àwọn ìlò èdè wọ̀nyì làti fi ẹ̀hónú hàn. òǹkọ̀wé fi ìlò èdè yìí sí ẹnu àwọn ẹ̀dá ìtan wọ̀nyí, kí àwọn mẹ̀kúnnù ní àwùjọ Nàìjíríà le mọ̀ pé ojú bọ̀rọ̀ kò ṣe gba ọmọ lọ́wọ́ ẹ̀kùrọ́.

Ṣíwájú sí i, òǹkọ̀wé lo ìfohunpènìyàn làti fi bí àwọn ajìjàgbara ṣe fi ẹ̀hónú hàn. Ẹnu ọ̀kan lára àwọn òýtayò ni òǹkọ̀wé fi ìlò èdè yìí sí. Ó ní:

> Ìjọba ń pe ogun. Wọn ń ránṣẹ sí ọ̀tẹ̀, ọ̀tẹ̀ kò sí ní pẹ́ bá wọn lálejò. Ṣùgbọ́n bí ọ̀tẹ̀ bá dé, kó dájú pé apá wọn yóò káa (o.i. 42)

Bákan náà ní òǹtayò mìíràn tún fí ẹ̀hónú tirẹ̀ hàn làti tako ìjọba arẹ́nijẹ àti amúnisín. Ó ní:

> Dákẹ́ ẹnu rẹ, aláìmọ̀kan ẹ̀dá…ó bá sinmi jíjẹ agbọ̀nrín èsí nínú ọbẹ̀. Ayé ti lu jára, Olúkúlùkú ti mọ ẹ̀tọ́ rẹ̀. Ará oko ọjọ́sí ti di ará ìgboro. Àsìkò náà tidé làti jàjàgbara kúrọ̀ lọ́wọ́ amúnisìn. Bó lẹ̀ dogun kó dogun, bó lé dìjà kó dìjà. Ódá mi lójú pé ẹlẹ̀mìí ni yóò "last". "Shine "Your ears" la etí rẹ̀ kí ó gbọ́ ohun tó ńlọ (o.i. 42-43)

Òwe, ìtakora (Ará oko àti ará ìgboro), àwítúnwí (Dogun, dogun) (díjà, díjà) àti àmúlùmọ́là kóòdù (èdè) ni Ògúnlọlá lò nínú àyọlò òkè yìí làti fi bi àwọn tí à ń réjẹ ṣe fi ẹ̀hónú hàn. Ohun ti èyí ń túmọ̀ sí ni pé ojú gbogbo àwọn òṣìṣẹ́ ti là, wọ́n ti mọ ọ̀nà àti ète tí àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisìn máa ń tọ̀ láti fi rẹ́ ará ìlú jẹ. Ẹ̀dá ìtàn yìí kò kọ́ ohun tí yóò dà, ìdí nìyí tó fi sọ pé "Bó lè dogun kó dogun, bó lè dìjà kó dìjà". Irú ìlò èdè tí àwọn arẹ́nijẹ àti amúnsìn kò fẹ́ nìyí àti pé irú ìpèdè yìí náà ni àwọn agbátẹrù tíọ́rì Karl Marx ń fọn rere rẹ̀, ìpèdè tí yóò mú àwọn mẹ̀kúnnù ja àjàbọ́ kúrò lóko ìṣẹ́, ìyà àti òṣì. Nínú ìjìjàgbara èyí tí ó wáyé, òǹkọ̀wé lo èdè láti jẹ́ kí á mọ ìṣesí àti ìhùwàsí àwọn ajìjàgbara. òǹkọ̀wé ní:

> Àgbáríjọ ẹgbẹ́ òsìṣẹ́ ọba pàápàá kò dákẹ́. Wọn fàáké kọ́rí pé bí ikún lóloko, bí pàkúté ni ìpàdé dàálà. Dandan lówó orí, ọ̀ran-an-yàn laṣọ ìbora (o.i. 62).

Ìpèdè yìí fihàn pé àwọn òṣìṣẹ́ figa-gbága pẹ̀lú ìjọba arẹ́nijẹ àti pé dandan àwọn gbọ́dọ̀ bọ́ lóko ìrẹ́jẹ àti ìmúnisìn. Bẹ́ẹ̀ ni gbogbo ẹ̀tọ́ àwọn gbọ́dọ̀ jẹ́ sísan. Kókó ìlò èdè yìí ni pé kí àwọn mẹ̀kúnnù má dákẹ́, bẹ́ẹ̀ ni wọn kò gbọdọ̀ káwọ́ gbera. Àtipé irúfẹ́ ìlò èdè yìí tí àyọrísí rẹ̀ jẹ́ aáwọ̀, wàhálà, ìfẹ̀hónúhàn àti ìfàáké kọ́rí ni Ògúnlọlá ń pè fún. "Wọ́n fi ààké kọ́rí" túmọ̀ sí pé wọ́n kọ̀ jálẹ̀ pé dandan àwọn yóò kojú àwọn arẹ́nijẹ pẹ̀lú ìjìjàgbara. Dandan àwọn gbọ́dọ̀ gba òmìnira, àwọn sì gbọ́dọ̀ gba ẹ̀tọ́ àwọn lọ́wọ́ àwọn arẹ́nijẹ àti amúnisìn. Síwájú síi, nígbà tí ìjìjàgbara bẹ̀rẹ̀, àwọn òṣìṣẹ́ ṣe àwọn aṣòfin bí ọṣẹ ṣe ńṣojú. Òǹkọ̀wé lo èdè láti jẹ́ kí á rí i bí àwọn ajìjàgbara ṣe lu àwọn olóṣèlú arẹ́nijẹ àti amúnisìn. Òǹkọ̀wé ní:

> Nínà kò tó wíwọ́, ìyà tó jẹ wọ́n lọ́jọ́ náà, ó ju ti Màlùú tó kángun sí Fúlàní lọ (o.i. 51).

Ìpèdè yìí fihàn pé àwọn òṣìṣẹ́ fi ojú àwọn amòfin rí màbo. Òǹkọ̀wé fi àwọn arẹ́nijẹ wé Màlùú, bẹ́ẹ̀ a sì mọ̀ pé Màlùú tí ó bá súnmọ́ Darandaran (Fulàní) máa ń rí ìyà jẹ, ju màlùú tí ó bá jìnnà sí Fúlàní lọ. Àwọn òṣìṣẹ́ ni Fúlàní tí wọ́n ń fi ìyà jẹ àwọn Màlùúú (arẹ́nijẹ àti amúnisìn). Fún ìdí èyí, àwọn amòfin arẹ́nijẹ-múnisìn rí imú he ètè wọn sọnù ní ọjọ́ tí àwọn òṣìṣẹ́ kógun tìwọ́n. Ìlò èdè Ògúnlọlá lọ tààrà. Ó sì mú ìtàn náà jọ ìtàn ojú ayé.

**Àgbálọgbábọ̀**

Iṣẹ́ yìí ti ṣe àgbéyẹ̀wò díẹ̀ lára àwọn àkànlò èdè ayàwòrán èyí tí Layọ̀ Ògúnlọlá ṣàmúlò nínú iṣẹ́ ọnà aláwòmọ́ lítíréṣọ̀. A sì ti fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé bí omi àti aró ni iṣẹ́ ọnà àti àkànlò èdè ayàwòrán jẹ́ sí ara wọn. Kò sí ijọ ò kun ni ìlò èdè jẹ́ sí ẹ̀ka lítíréṣọ̀ mẹ́tẹ̀ẹ̀ta. Èdè ni a fi ń hun iṣẹ́ ọnà lítíréṣọ̀. Irúfẹ́ èdè yìí sì gbọ́dọ̀ jẹ́ èyí tí ó jinlẹ̀, tí ó sì jẹ́ àṣàyàn. Àriwòye àpilẹ̀kọ yìí ni pé ìṣàmúlò àwọn àkànlò èdè ayàwòrán wọ̀nyí ti ń di ohun ìgbàgbé. Iṣẹ́ àpilẹ̀kọ yìí dá àbá fún àwọn òbí kí wọ́n jẹ́ kí àwọn ọmọ wọn máa kọ́ èdè Yorùbá, èyí kò ní jẹ́ kí èdè wa pàápàá jùlọ àwọn àkànlò èdè ayàwòrán tó sodo sínú àká èdè Yorùbá sọnù pátápátá. Bó tilẹ̀ jẹ́ pé ìṣàmúlò àkànlò èdè ayànwòrán tí n dìmẹ́rí, látàrí àìkárámàsìkí èdè abínibí,

àpilẹ̀kọ yìí tún mú un wá bí àbá fún ìjọba àpapọ̀, kí wọn ṣàmúlò àyájọ́ ọjọ́ èdè abínibí lágbàáyé èyí tí àjọ UNESCO gbé kalẹ̀, tí wọ́n sì ya ọjọ́ kọkànlélógún oṣù keji ṣọ́tọ̀ gẹ́gẹ́ bí àyájọ́ èdè abínibí lágbàáyé.
Bó ti lẹ̀ jẹ́ pé ọ̀pọ̀ yanturu ní àwọn orílẹ̀ẹ̀dè tí ó jẹ́ ọmọ ẹgbẹ́ yìí ní abẹ́ ìsọ̀kan àgbáyé, ni wọ́n ń ṣàmúlò àyájọ́ ọjọ́ èdè abínibí yìí ní ọdọọdún, ṣùgbọ́n orílẹ́ẹ̀dè Nàìjíríà kò mú ọjọ́ yìí ní ọ̀kúnkúndùn, àyàfi àwọn ẹgbẹ́ onímọ̀ èdè Yorùbá. Nípa kíkáràmásìkí èdè abínibí wa, ìdánilójú wà pé àwọn àkànlò èdè ayàwòrán tí ó sodo sínú àká èdè Yorùbá kò ní lọ sí òkun ìgbàgbé. Ònà mìíràn tún ni pé, kí àwọn òǹkọ̀we lédè Yorùbá máa gbé ìwé jáde lórí àkànlò èdè Yorùbá, Kí ìdíje sì máa wà fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ lórí àkànlò èdè ayàwòrán Yorùbá. Ní ìparí, iṣẹ́ yìí dábàá fún àwọn akẹ́kọ̀ọ́ tó ń kọ́ ẹ̀kọ́ Yorùbá, àwọn olùfẹ́ èdè Yorùbá, àwọn ilé iṣẹ́ rédíò àti tẹlifísàn tí ń gbé èdè Yorùbá lárugẹ láti máa ṣe àmúlò àwọn àkànlò èdè ayàwòrán wọ̀nyí nínú ìgbòkègbodò wọn lójoojúmọ́, nípa síṣe èyí, èdè wa kò ní lọ sí oko ìparun.

## Ìwé Ìtọ́kasí


Adéyẹmí, L. (2006). *Tíọ́rì Lítíréṣọ̀ ní Èdè Yorùbá*: Ìjẹ̀bú Òde: Shebiotimo Publication.

Adéyẹmọ, O. (1997). *Obìnrin Nínú Eré Onítàn Ládojúdé: Rẹ́rẹ́ Rún àti Abẹ́rẹ́ Oró Bí Àpẹẹre*, M.A Project: Ìlọrin, University ofÌ lọrin.

Adéọ̀sun, H. O. (2005). *Lítíréṣọ̀ àti ètò ọrọ̀ ajé àwùjọ nínú àwọn ìwé ìtàn àròsọ Fágúnwà.* M.A Project University of Ilorin, Ilorin.

Agu, I. E. (2008). *Introduction to literary criticism*. Yola: Paraclete Publishers.

Eagleton, T. (1996*). Literary theory: An introduction* (2nd Edition). Minneapolis: University of Minnesota Press.

Gidden, G. (2006). *Sociology*. Ibadan: Polity Success Consult.

Ògúnlọlá, L. (2013). *Kò sọ́rọ̀*. Ì lọrin: Chridamel Publishing House.

Oyèrìndé, O. àti Álímì, K. (2011). *ÀKànlò èdè Ayàwòrán nínú Lítíréṣọ̀ Yorùbá*: *Máyàmí fún olùkọ́ àti akẹ́kọ̀ọ́.* Ibadan: Standard Publication.

Ọ̀pẹ̀fèyítìmí, A. (1997). *Tíọ́rì àti ìsọwọ́lò-èdè.* Òṣogbo: Tanimẹ̀yìn-Ọ̀la Press.



Recebido em: 20/07/2025
Aceito em: 13/08/2025



**Para citar este texto (ABNT):** AKINLABÍ, A. Williams. Àgbéyẹ̀wò orísirísi ìlò èdè tí ó jẹyọ nínú ìwé ìtàn àròsọ *kò sọ́rọ̀* tí layọ̀ ògúnlọlá kọ. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial II, p.143-153, jul./dez.2025.

**Para citar este texto (APA):** Akinlabí, A. Williams. **Àgbéyẹ̀wò orísirísi ìlò èdè tí ó jẹyọ nínú ìwé ìtàn àròsọ *kò sọ́rọ̀* tí layọ̀ ògúnlọlá kọ.** *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.*São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial II): 143-153.